NYC Mayor's Office of Immigrant Affairs

# Ilé ẹjọ́ Ìwọléwọ̀de 101

Yoruba | Yorùbá

Ní **Ilé ẹjọ́ Ìwọléwọ̀de**, o máa ní àǹfààní láti gbèjà ẹjọ́ rẹ níwájú adájọ́ tó ń rí sí ọ̀ràn ìwọléwọ̀de, ki o sì ṣàlàyé ìdí tó fi yẹ kí a gbà ọ láyè láti máa gbé lórílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà. Ti o bá pàdánù ẹjọ́ rẹ ní ilé ẹjọ́ ìwọléwọ̀de, o lè pe ẹjọ́ kòtẹ́milọ́rùn.

**A lè lé ọ kúrò nílùú, tí:**

- o bá pàdánù ní ilé ẹjọ́ ìwọléwọ̀de, tí o kò sì pe ẹjọ́ kòtẹ́milọ́rùn,
- o bá pe ẹjọ́ kòtẹ́milọ́rùn, tí o sì pàdánù.

## Ta ló máa wà ní ilé ẹjọ́ ìwọléwọ̀de?



- **Onídájọ́ Ìwọléwọ̀de** tí ó máa pinnu bóyá a máa gbà ọ láyè láti dúró ní orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà máa wà níbẹ̀.
- **Agbẹjọ́rọ kan** tí ó ń ṣiṣẹ́ fún ìjọbá máa wà níbẹ̀. Iṣẹ́ wọn ni láti ṣojú ìjọba Orílẹ̀-Èdè Amẹ́ríkà. Wọn kò ṣiṣẹ́ fún ọ.
- **Tí o bá ní agbẹjọ́rọ̀**, wọ́n lè wà pẹ̀lú rẹ ní gbọ̀ngàn ilé ẹjọ́ nígbà gbogbo, wọ́n sì lè pè ọ́, kí wọ́n sì wá bẹ ọ́ wò.

**Rántí: Ijọba kò ní pèsè agbẹjọ́rò fún ọ, ṣùgbọ́n o lè gba agbẹjọ́rò láti ṣojú rẹ ní ilé ẹjọ́.**

## Yíyẹ dééti ilé-ẹjọ́ ìwọléwọ̀le rẹ wò

- Láti yẹ dééti ilé-ẹjọ́ rẹ wò, o máa nílò nọ́mbà-A (A-number) rẹ. (Àpẹẹrẹ: A 000-000-000). Ìjọba ló máa ń fúnni ní nọ́mbà yìí, ó sì máa ń wà nínú àwọn ìwé àṣẹ ìrìnnà.
- Yẹ àwọn àlàyé fún ìgbẹ́jọ́ rẹ wò nípa lílo Ètò Àlàyé Nípa Ejọ́ Aládàáṣiṣẹ́ (Automated Case Information system). Àwọn ọ̀nà méjì rèé ní ìsàlẹ̀:
  - Pe nọ́mbà ìbánisọ̀rọ pàjáwìrì lórí 1-800-898-7180. Tẹ nọ́mbà-A rẹ sínú rẹ̀, kí o sì tẹ̀lé àwọn ìtọ́ni oníṣẹ́ náà.
  - Kàn sí ojú ìkànnì ayélujára(webpage): https://acis.eoir.justice.gov/en/. Tẹ nọ́mbà-A rẹ sínú àpótí ìṣàwákiri kí o sì tẹ̀ "Enter" (Tẹ̀ẹ́ wọlé).

**Ìwé ìléwọ́ yìí ń fúnni ní àwọn àlàyé gbogboogbò nìkan. Kìí ṣe ìmọ̀ràn nípa òfin. Kàn sí agbẹjọ́rò fún ìmọ̀ràn nípa òfin.**

Mayor's Office of Immigrant Affairs

# Ilé ẹjó Ìwọléwọ̀de 101

Yoruba | Yorùbá

## Pípààrọ̀ ìgbẹ́jọ́ ojúkojú rẹ sí ìgbẹ́jọ́ órí afẹ́fẹ́/tẹlifóònù

Bí o bá fẹ́ pààrọ̀ ìgbéjọ ilé ẹjọ́ ìwọléwọ̀dé ojúkojú rẹ sí orí ayélujára tàbí lórí tẹlifóònù, o ní láti fi ìbéèrè kan ránṣẹ́ sí ilé ẹjọ́. Ó ṣe pàtàkì láti fi ìbéèrè náà sílẹ̀ ní kíákíá tó bá ṣeé ṣe, kó tó di ọjọ́ ìgbẹ́jọ́ tí ó kàn. Ní ṣíṣe bẹ́ẹ̀, o gbọ́dọ̀ rántí láti **kàn sí agbẹjọ́rò kan**.



- Ìmọ̀ràn nípa òfin gbọ́dọ̀ wá láti ọ̀dọ̀ agbẹjọ́rò, ẹni tó lè ràn ọ́ lọ́wọ́ láti ṣètò àti láti kọ àwọn ìwé tó yẹ lọ́nà tó tọ́.
- O máa nílò láti fi Ìbéèrè sílẹ̀ láti Yí Ọ̀nà Ìgbẹ́jọ Padà (Motion to Change Hearing Format) pẹ̀lú ilé-ẹjọ́. Onídàájọ́ tó n rí sí ẹjọ́ ìwọléwọ̀de máa ṣàyẹ̀wò ohun tí o béèrè, yóò sì fi ìpinnu náà tó ìwọ tàbí agbẹjọ́rò rẹ létí.
- Tí a bá fọwọ́sí ìbéèrè náà, ìgbẹ́jọ́ náà máa wáyé lorí ayélujára; tí a bá kọ ìbéèrè náà, ìgbẹ́jọ́ náà máa wáyé ní ojúkojú.

## Wíwá Aṣojú Òfin

Ní àwọn oṣù tí kò tíì pé, a tí gbọ́ àwọn ìròyìn nípa ìgbòkègbodò ìmuṣẹ òfin ìwọléwọ̀de nínú àwọn ilé ẹjọ́ ìwọléwọ̀de. O lè fẹ́ láti ṣètò kan sílẹ̀ tí ó bá ṣẹlẹ̀ pẹ̀ a dá ọ dúró. Tí o bá ní ìbéèrè, bá agbẹjọ́rò kan sọ̀rọ̀.

**Fún ìrànlọ́wọ́ ọ̀fẹ́ nípa àṣírí òfin ìwọléwọ̀de pé ìlà pàjáwìrì Àtìlẹyìn nípa Òfin ti Ọ́fíìsì Ọ̀gá Àgbà Tó n rí sí Ohun tó ní ṣe pẹ̀lú Àwọn awọléwọ̀de (Mayor's Office of Immigrant Affairs, MOIA):**

**1-800-354-0365**

Ọjọ́ ajé sí Ọjọ́ Ẹtì, 9AM sí 6PM     Ògbufọ̀ wà

Ilé ẹjọ́ Ìwọléwọ̀de kọ̀ọ̀kan ní àtòjọ àwọn olùpèsè iṣẹ́ òfin ìwọléwọ̀de tí ó jẹ́ ọ̀fẹ́ tàbí tí owó wọn kò wọ́n nítòsí.

Ṣàyẹ̀wò kóòdù QR náà láti wo atòjọ àwọn àjọ amòfin ìwọléwọ̀de tí ó jẹ́ ọ̀fẹ́ nítòsí ilé ẹjọ́ rẹ sílẹ̀ tàbí kí o kàn sí: www.justice.gov/eoir/list-pro-bono-legal-service-providers

**Ìwé ìléwọ́ yìí ń fúnni ní àwọn àlàyé gbogbogbò nìkan. Kìí ṣe ìmọ̀ràn nípa òfin. Kàn sí agbẹjọ́rò fún ìmọ̀ràn nípa òfin.**